The Honourable
The Chief Secretary to Govt.
Chief Secretary's Office
Lagos

D. A. Obasa
Editor & Proprietor
"Yoruba News"
Ogunpa Rd.
Ibadan


# THE Yoruba News.

FOR GOD, THE KING AND THE PEOPLE.

VOL. VI. No. 20. NEW SERIES. IBADAN, July 30, 1929. Price 3d. Weekly



## WHY make your Car LABOUR?

Get a Tank-full of

# ATLANTIC MOTOR SPIRIT,

## THE BALANCED PETROL

that makes every Motor easy to START

Smooth to RUN, and gives you the BIGGEST MILEAGE.

If you want your motor to be a paying proposition ☞ DO IT NOW.

## WHY be miserable?

Make your Home Bright and Cheery by burning

**ATLANTIC KEROSENE**

Obtainable From

Messrs Paterson Zochonis & Co. Ltd., (Sole Agents.)

LAGOS and Branches

---

KIL' O NDÃMU MOTO RE LASAN SI?

Bi o ba ti nrọ arọkun Epo

# PETROL TI "ATLANTIC"

Si inu Tanki Epo Mọto rẹ.

Ko s' ewu mọ; pẹlu irọrun ni Motọ yio ma fi sure lọ gerere si ibikibi l' aisọsẹ Bi o ba nfẹ Erè pupọ lori iṣẹ ti o nfi Mọto rẹ ṣe, din inọwo Epo Mọto ku nipa lilo

☞ **Petrol ti "Atlantic."**

---

ILỌ O! ALỌ O!! "Aja dudu gba 'le gb' ode?":— Okunkun ni jẹ bẹ na wọle Okun parada!" Le õkun jade nipa fifi **"Atlantic" Kerosene** Ororò t' o jire tan gbogbo Atupa rẹ. OIBO ALAGBỌN ni nta a ni Eko ati ni gbogbo ibi ti Ile Owo wọn gbe wa **SA DAN A WO**

**A. B. LAWANSON, & BROS.**

*General Contractors,*

Alafara Street. Box 172, IBADAN.

**Constructors of Railroad Permanent Ways, Motor Roads, Embankments, Cuttings, Bridges, Culverts, Road Repairs &c..**

***Orders promptly and accurael executed.***

Trial Order solicited.



# J. D. E. ABIOLA Co.,

General Merchants, Proprietors of Motor Transport Service, Road & Building Contractors

OKE—OMOFE, & ORIKIRAN ST.

ILESHA

And also Fancy Shop at Ersja Market,

***DEALERS IN***

various articles for Reo Motor Different sizes of Tyres 35x5 33x5 Tyres and Tubes Dunlop and Michelin Tyres.

Petrol, Engine Oil, Gear Oil, Grease, & Spare Parts.

Cotton Goods, Corrugated Iron Sheet Cement &c..

ALWAYS IN STOCK.

Best quality, and, the Cheapest Store,

ORIKIAN STREET ILESA.

COME ONE COME ALL


## Dissolution of Partnership.

It is notified for general information that partnership between Messrs. C. J. Mellon and George Kapsopulos, Contractors, of the Gold Coast and Nigeria in West Africa has been dissolved as from the 29th June, 1929.

GEORGE KAPSOPULOS.

Ibadan, 4th July 1929

# OWUYẸ.

Ni irọlẹ Wednesday ọjọ kẹrindilogun osu yi ni a gbọ iku Durojaiye oloye Mayẹ Balogun ni agogo mẹrin ābọ ati okiki kan wipe "Ibōsi aje o!' Mayẹ Balogun ti o ṣẹṣẹ joye owo osu kan na koi ti fi jẹun tan ni onikọ iku ba de lojiji. Ati tufọ fun Arabadan dogun, wipe: " ā ti igbọ? A ro pe awọn onkawe wa yio ro bi ologbe nā ti ṣe joye

Idagiri da ni Gbagi ati Ekotẹlo ni ọsan ijẹrin Satide, July 27, nigbati a gbọ iku Iyafin Rachael Morohundiya aburo Ọgbẹni James Jones ti o ti Eko wa wo aburo rẹ Mrs. J. B. Abimbọla ẹniti o ṣẹṣẹ bimọ laipẹ yi. Ohun iyanu ni pe, ọjọ ti Ologbe nā ti ranṣẹ si ọkọ rẹ pe oun o pada si Eko gān l' o jaisi nihin — ani o tilẹ ti npalẹ mọ ati lọ wọ ọkọ Reluwẹ ti Saitde nā papa. Oru ki ilẹ to mọ ṣa ni a gbọ pe obi ntẹ ẹ, ti o si bimọ lai si inira rara. Ko pẹ lẹhin ti o jẹun diẹ tan ni onikọ iku de. A sin oku rẹ ni Ọgba Sọṣi Ogunpa ni Sunday ana.

Ologbe na fi ọmọbirin mẹrin ati ọmọkunrin kan pẹlu awọn ẹgbọn, aburo silẹ ninu ọfọ nla.

A ki awọn Ogbẹni James Jones, J. B. Abimbọla ati Mrs. M. M. Abimbọla pẹlu Ogbẹni Phillips ti Ebute Meta Ẹ ku ọfọ, Ẹ ku ajalu. Ki Oluwa f' ọrọ mọ bayi, ki O si da awọn ọmọ oku si.

Awọn Oibo titun (Cadets) mejila de si Oke Ajẹlẹ fun iṣẹ Ijọba Ọdọmọkunrin ti o ṣẹṣẹ jade ni Ile-ẹkọ Giga *University* Ilu Gẹsi ni nwọn. Mẹsan ninu nwọn lọ si Ọyọ, mẹta yoku duro si Ibadan lati kọ iṣẹ Ijọba. Ẹ kabọ o!

Ogboju Ole ti Njare Olohun.

O ya ni lẹnu lati ri obirin kan ti nkigbe pẹlu itara ni dede agogo mẹta abọ ọsan Friday ni popo Amunigun pe: awọn ogbologbo ole wọ ile oun, ti nwọn si ko ẹru rẹ ati ọja oṣu ti o ṣẹṣẹ gba la na lọ

Ẹnyin enia wa ẹ ma jafara o, awọn tun de o.

Yoruba ni Kano.

Ọmọ Titun Alejo Aiye.

A ki Ọgbẹni Moses Popoọla ati awọn ẹbi tẹ barika fun ọmọbirin ti Ọlọrun fi ta oun ati aya rẹ lọrẹ ni Mọnde Julai 8/7/29. O si ṣe inawo Ikojade ọmọ na ni ọjọ Mọnde 15/7/29. Irohin ko to afojuba ni arakuyamu inawo na. Ki Ọlọrun da ọmọ na si ki o si ṣe e ni ọmọ rere ti yio rọlọ baba rẹ lẹhin ọla.

'Nda ọmọ Tapa (about 10 years of age)
Jibiriu ọmọ Yoruba (about 9 years of age)
Saleko ,, ( ,, 8 ,, ,,

Awọn ọmọ mẹtẹta ti a daruko soke yi fi ara wọn joye Iasansa ati Alarinkiri ni igboro Sabongeri, Kano, lọde Reluwe Teṣan. Nwọn lọ ji pọmpu Baisikulu Saji (Sergeant) Ọlọpa kan ti njẹ Garuba Zaria yọ ni Reluwe Teṣan ni ọjọ 6 oṣu Julae yi, nigbati Saji na gbe Baisikulu rẹ na ti, ti o si nṣe iṣẹ rẹ kakiri Teṣan ki ero ẹkọ ọjọ Satide na to ṣi; ṣugbọn ọwọ bà awọn ọmọ Jàgùdà na, wọn ko wọn lọ si ile ẹjọ. Bi wọn ti jẹ ọmọ kekèke, adajọ da seria billàà mẹfa-mẹfa fun wọn ni ọjọ 11 oṣu yi.

Ẹnyin Yoruba Sabongeri tabi ti igboro Kano, ẹ toju awọn ọmọ nyin o. Kini k' a ti gbọ pe ọmọ Yoruba dapọ mọ awọn ọmọ Hausa ati Tapa-a-ji-ma-ni-'ṣẹ, ki wọn si di ẹgbẹ ole lati arọ kutukutu wọn?—Ẹni biui l' a jọ o, ābọ ọrọ,

Ijọ Holy Trinity, Kano, Ẹ ku Alejo o.

Ni aro ọjọ Furaide 19/7/29 ni Mr. S. O. Odutọla B.A., D.Th pẹlu aya rẹ apọn b'epo rẹ, opẹlẹngẹ awẹlẹwa, ba ọkọ de. Mr. Odutọla ni ẹniti awọn Nigeria Pastorate Association ran wa lati ma ṣiṣẹ gẹgẹbi Katikist larin Ijọ ti a daruko loke yi, o ṣẹṣẹ ti Saro de ni lẹhin ti o ti lọ ti gba oye, Irun aguntan, A ni ireti pe awọn Alaṣẹ yio tete fun u ni oye Alufa ki o le di Ijọ rẹ mu daradara.

## IROHIN ILE BALE

Monde 29, 1939.

Awọn Ọmọ Dada ti nja si ile riro lẹhin iku Adeaga Osi Balẹ, eyiti Balẹ ati Igbimọ ti fi ipinnu si pe ki apa kinni: eyi ni Ajibikẹ aburo alaisi Adeaga, ati apa keji, eyi ni Fakayọde ọmọ alaisi Adeaga o lọ si ọdọ Ajẹlẹ ki o tika ara rẹ yan ẹniti o ba tọ ninu wọn, ki wọn o si mu abọ rẹ pada wa. Awọn Igbimọ si yan onisẹ tẹle wọn; nwọn wa fi abọ fun awọn Igbimọ loni Onisẹ ti wọn yan tẹle awọn mejeji yi jisẹ fun awọn Igbimọ pe, Fakayọde ni Ajẹlẹ ro pe o tọ si. Lẹhin ti onisẹ yi jisẹ tan ni Ajibikẹ si dide, o ni oun papa o ko lahiri ile riro; se Fakayọde na ni o ke si oun nigbati ẹgbọn oun kosi pe. ipo na kan oun, eyiti o mu oun ma kówó kūkiri lati fi sinku ? ti o ba si wa di pe ọrọ ko ri bẹ mọ, ki Balẹ ati Igbimọ ba oun bere bi owo ti awọn kó yio ti se jẹ sisan. kò si kúkú si eyiti o sé ẹhin rẹ nibẹ. Awọn igbimọ si sọ fun wọn bayi pe: Inkan ti o ba ti tọ ni oju oibo ko yẹ ki awọn o tun mā topinpin rẹ mọ; sugbọn ki Fakayọde lọ ba wọn mojuto ati san owo ti nwọn ko sinku, nitoripe awọn ro pe ko tọ lati wi fun aburo baba wọn (Ajibikẹ) ki o mā lọ san owo na lori asan.

Ajẹlẹ kọwe si Balẹ ati Igbimọ pe ki wọn o ransẹ lọ pe Balẹ Inisa wa siwaju wọn, ki wọn si kilọ fun u pe o ni lati mā tẹriba fun Balẹ Okuku ati pe, ki o si mā se bi o ti tọ ati bi ọ ti yẹ si i. Awọn Igbimọ si da esi pada pe awọn o se bẹ: lẹhin na nwọn pe akọda kan pe ki o lọ pe Balẹ Inisa na wa, ti o ba si nlọ ti o ba dé Okuku, ki o sọ fun Balẹ ibẹ pe Balẹ Inisa ti nyaju si i na ni awọn ni ki o lọ pe wa fun awọn yi; ati pe ki o si ran diẹ ninu awọn Ijoye rẹ, ki gbogbo inkan ti awọn o ba ba Balẹ Inisa na sọ le ṣ' oju awọn enia rẹ, ki wọn ba le lọ fun u ni abọ pada

Ajẹlẹ kọwe si Balẹ ati Igbimọ nipa iwe ti nwọn kọ si i pe awọn fẹ ki oun o ransẹ lọ pe Balẹ Ọdẹomu fun awọn; o ni oun kọwe si Balẹ Osogbo ẹniti ilu na wa labẹ itọju rẹ, sugbọn oun koi ti ri esi gba lati ibẹ, bi oun ba ri esi gba, oun o jẹki awọn Igbimọ o gbọ. Awọn Igbimọ si tun kọwe pada pe ohun ti o jẹki awọn o wipe awọn fẹ ri Balẹ Ọdẹomu nipe, nipa ija oko ti ara Ẹdẹ ati awọn ara Ọdẹomu yi: ki ise oni ni nwọn ti i mā ba ara wọn ja bẹ: awọn nā ni awọn nba wọn ipari rẹ. Awọn yan onisẹ lọ se āla fun wọn, awọn ti pari ija ti ikehin yi fun wọn nisisiyi ko ti ju idunta lọ. nitorina ni awọn fi nfẹ ki Balẹ Ọdẹomu o wa sọ ti ẹnu rẹ fun awọn ati ki o si tun sọ fun awọn bi āla eyiti awọn ti se fun wọn ni nwọn nja si ni o, bi omi ni o: awọn a mọ, awọn a si tun ran awọn ti awọn ran lọ se āla fun wọn ni idunta lọ yẹ ẹ wo ki awọn o le mọ ẹniti nse abosi ninu awọn mejeji. Nitori ija wọn na nto ẹmẹfa nisinyi: o si tete fẹ amoju to.

Ajẹlẹ kọwe si Balẹ ati Igbimọ pe ọkunrin kan ti orukọ rẹ njẹ Adeyẹmọ ba awọn onisẹ awọn Igbimọ wa si ọdọ oun o si fi ẹsun ọkunrin kan ti njẹ Kanhinde siwaju oun pe, Kanhinde yi ni ọpọlọpọ Ẹlẹdẹ; igba gbogbo ni awọn ẹlẹdẹ wọnyi si mā nba inkan awọn jẹ: bi awọn ba si wi fun u ki i su ja a. Inkan oun ti awọn ẹlẹdẹ wọnyi wa ba jẹ nikanyin yi ka oun lara, nitori nigbati oun siro gbogbo rẹ o jẹ inkan pọnun mẹwa Ajẹlẹ ni, nigbati oun wa idi ọrọ na, oun ri i pe Ọgbẹni Kanhinde na ni to ẹlẹdẹ mẹsan, oun si rope wọn le ba inkan ti o to bẹ jẹ. Sugbọn nigbati oun bi Kaninde lere, o ni irọ ni ati pe Adeyẹmọ yi ati awọn enia rẹ ti nditẹ ati le oun lọ ti pẹ, nitori oun jẹ ara Abẹokuta. Oun Ajẹlẹ si fẹ ki Balẹ ati Igbọn wa idi ọrọ na, ti o bajẹ tōtọ ni nwọn dirẹ si ọgbẹni na ni, ki awọn Igbimọ o mā jẹki wọn o le e lọ o. Awọn Igbimọ si da esi pada pe bi ko fẹ, ki wọn le ọgbẹni na lọ ki o sọ fun u ki o lọ san owo inkan ti ẹlẹdẹ rẹ bajẹ fun Adeyẹmọ ẹniti o mu ẹsun wa, nitoripe inkan pọnun mẹwa kuro ni a mu oju kuro rara, ti o ba san owo tan, awọn o

ko lọ fun wọn pe wọn ko gbọdọ le e.

Ajẹlẹ kọwe bere lọwọ Balẹ ati Igbimọ nipa iwe ti oun kọ si wọn nipa Aminu ẹniti awọn ara Gbọngan ni awọn fẹ fi jẹ Oye Otun Balogun ni Gbọngan; kinni nwọn ti ro ọrọ na si? Awọn Igbimọ si dẹsi pada pe o dun mọ awọn ninu, ki nwọn fi jẹ ẹ.

Ajẹlẹ kọwe pe, iwe eto oye jijẹ ti oun fi sọwọ yi, Ajẹlẹ Agba ti fi esi bayi pe ki Asipa Balẹ jẹ Otun Balẹ, ki Ekẹrin Balẹ jẹ Osi Balẹ, ki Adebisi Giwa Maye Balẹ jẹ Abẹsẹ Balẹ, ati pe nigbati nwọn ba fẹ jẹ ẹ ki wọn ranṣẹ si oun. Awọn Igbimọ si bi akọwe lere pe esi iwe wo ni Ajẹlẹ fesi si i; eyiti awọn kọkọ tabi ti ikanhin? Akọwe si dahun o ni ti akọkọ ni.

Miss Macaulay ati Ọgbẹni Thomas ti a ti sọ nipa iwe wa ti ọsẹ kẹta tun wa siwaju Igbimọ loni; obinrin nā ẹniti awọn Igbimọ ni ki o mu iwe adehun ti nwọn jọ se wa, bi o ba jẹ tọtọ ni ọkunrin nā jẹ ẹ ni owo, mu iwe na wa; nigbati ẹjọ yi kan wọn, obinrin yi dide, o si yira fun awọn Igbimọ o sọ fun wọn pe: lati ọjọ ti awọn ti kuro ni iwaju wọn pe ki oun lọ mu iwe wa, sisapamọ ni oun ti sapamọ, nitoripe bi awọn ti jade bẹni ọkunrin na bẹrẹ si leri pe: ni ọjọ ti oun ba mu iwe na wa pade rẹ ni Apẹjọ, pe, pipa ni oun o pa oun.

Balẹ ati awọn Igbimọ si pe ọkunrin nā bi pe: sẽ nitọtọ ni o fẹ buwa buruku bẹ? O ni oun kọjẹ huruwa bẹ rara. Awọn Igbimọ wa ro ọrọ nā wo, wọn si kesi akọwe Igbimọ pe ki o ba wọn kọwe fun awọn mejeji ki wọn mu lọ ọdọ Ajẹlẹ, ki akọwe si sọ sinu iwe nā gẹgẹbi obinrin yi ti wi awọn. Nitoripe bi fun awọn ba ni ọkunrin yi ko le se bẹ, a si se e; awọn o si fẹ ki enikan wa pa enia siwaju awọn nihin. Nwọn si tun ro lọ kan ti Delphoso ati Lọya Abiyọmi nigbati o si ti jẹ pe ara Eko ni awọn mejeji. Nwọn ni ki Ajẹlẹ pāpa o da a fun wọn.

Ọgbẹni Bakare Williams ti a ti sọ ri pa ile ti awọn Ijọba Ibadan ni ki o kuro nibẹ kọwe si Balẹ ati Igbimọ, bayi pe: oun ti wa ni Ibadan nisiyi to ọdun mẹdọgbọn, oun si dupẹ lọwọ Ọlọrun ati Ibadan pe larin gbogbo ọdun ti oun daruko kosi idamu kankan fun oun afi odo Ogunpa ti o ja ti oko oun ni ile ati ẹru lọ,eyiti o da gbese ti o to ọdun pọnun si oun lọrun; oun si tun dupẹ ni idakeji ẹwẹ pe iye ti o ku ti oun ni san ninu ọdun pọnun na nisiyi ko ju adọta pọnun lọ mọ nitorina oun rope o yẹ ki awọn Ijọba o sanu oun nitori gbogbo inkan ti oun ri yi, ati pe oun ri iwe gba lati oke pe ki oun wa gba pọnun mọkanlelọgbọn fun ile ountti wọn gba fun Titi. Lori gbogbo ẹ' oun bẹ awọn Igbimọ ki won se iranwọ fun oun. Ṣugbọn awọn Igbimọ koi ti f' esi tāra si ọro nā.

Ajẹlẹ kọwe si awọn Igbimọ pe, oun ti lọ sẹ ãla fun Aminu Seriki ati Ọjẹ ti wọn nja si ãla oko o.

Igbimọ si desi pada pe o dun mọ awọn ninu; O ku abọ o.

## News and Notes.

Mr J. J. Tubi of the Administrator's Office, Lagos, came up to spend part of his leave with his family at Odo Iye, Ibadan. Mr Tubi who also travelled up the railway line as far as Zaria to see some old friends returned to town yesterday looking quite fit We say, Good Luck, old chap.

### MINNA.

Mr S. O. Adebanwa of the Loco Department at Offa who after his transfer to Gusau, had an attack of Yellow Fever for about two months lately The sickness was so much that he was reported to have succumbed to the dangerous malady. But thanks to Messrs. E. J. F. Oyedele and James Ijẹniwa who providentially rendered great assistance during the illness, it would have ended fatally.

### IFẸ.

The work of Ifẹ Water Supply is progressing and a splendid road is being made to Mokuro Spring, where the water is to be drawn.

We understand the Engineer Native Administration and the District Officer are busily engaged on this great work.

## THE YORUBA NEWS.

*Editor & Proprietor* ;
D. A. OBASA.
*Office* :—Ajaba Square, Ogunpa Road,
P. O. ox 60, IBADAN
***Subscriptions payable in Advance***
Ibadan 12s. per annum. 14s Post Free.
Cheques and Orders should be crossed and forwarded to the Editor.
Advertising rates &c. on application


## GOVERNMENT PRESS 1928.

THE Annual Report of the Government Printing Department for the year 1928 is an interesting document for every printer in this part of the world. It contains a detailed statement of the number of Departmental Forms, Books, etc., supplied and brought to account during the year 1928.

The decrease in the output of forms and miscellaneous items was more than compensated for by the increase in books, and the value of work done and brought to account during 1928 shows an increase of nearly £400; (£37,294. 6 10d against £36,904, 11. 5d. in 1927) for 6,460,307 Departmental Forms, 4 412 Receipt Books, 179,512 Pamphlets including Gazettes and supplements, 58,836 Books and Ledgers, 3755 General Orders, Staff List Hand Book Civil Service List, 1587 Blue Books and Estimates, 13491 Annual Reports and Sessional Papers, 375626 Miscellaneous. These quantities were printed off 3112 Formes of which 1802 were kept standing.

The efficiency of the staff, both European and African is all that could be desired. It is doubtful whether we could find anything approaching it in any part of British West Africa or rather in the whole of Africa, with the possible exception of Egypt and Cape Colony.

This Department has proved a beneficial institution to the country. Apart from revenue producing considerations, it has assisted the progress of our printing and book-binding trades in a way that reflects great credit upon the Government of Nigeria. This is testified to by the high class printing and book-binding regularly issued from the department and other private printing and book binding offices, the staffs of which have, in many cases, passed through it at one time or the other.

It is hoped the existing terms of apprenticeship in the department will be supplemented with one year's further instruction in some of the great printing establishments in England to enable deserving African cadets to obtain deeper insight into the different branches of the art of printing.

Mr. J. A. Blair, who succeeds Mr. De Boltz, is a capable and an experienced officer. We congratulate him upon his well-merited promotion.

## Ifa Aditi.

iv

Ọrọ ti o tun kan wa ni ti Ọpẹ tabi Igi Ọpẹ. Awọn ẹlomi le sọ pe, kil' o tun ba oniwe 'rohin de ibi ọrọ Ọpẹ ni siso ? Ṣe aiye l'a ba Igi Ọpẹ ? Tabi Ọpẹ wa kanna ti a mọ yi kọ ndan ?

Bẹni, ẹnyin ara wa, Igi Ọpẹ wa kanna yi ti nfun wa ni Epo ti a fi nse ọbẹ, tan ina, ṣe egbogi lila tabi pipara, ti a si nrọ si inu garawa lọ ta fun wọn ni Ọyọ, Isẹhin, Ṣaki, Ilọrin, Jebba, Oke Ọya ni ilu Hausa ; ti a si nkan mọ agba lọ ta fun awọn onisowo ti nmu u lọ ta ni Ilu Oibo ati Ekurọ ti awọn Oibo ti tori rẹ kan ọkọ ràgàjì-ràgàjì da si oju omi Okun. Ti a nfi ogunṣọ rẹ tan ina bi a ti nlo abẹ́là *candle* (ti a nra lọwọ awọn oibo nisisiyi); ti a nfi ē-an ati ihá rẹ da ina ; ti awọn alagbẹdẹ

nfi ẹyín rẹ ṣarọ; ti awọn iya wa nfi ēsan rẹ ṣe ilẹkẹ lagidigba olowo iyebiye latijọ: ti a nfi ọwa rẹ ró ile, ti a nfi ẹfọn rẹ hun agbọn ti a fi nru ẹru wa ile lati oko ati asẹ́ ti a fi nṣẹ ogi ati ẹlubọ: ti a nfi imọ rẹ kọ ile, ti a nfi ọwọ̀ rẹ ṣe igbalẹ ti nmu ki ile wa mọ toto: igbà ti a fi ngun Ọpẹ nā pāpa, igbagó ti a fi nda ina, lẹwù a ti fi nṣá ina (lara iṣana ti awa Enia Dudu) mariwò ti a nlo ni oniruru ọna ati pari-pari gbogbo rẹ, Ẹmu ti awa Ẹnia Dudu nlo gẹgẹbi awọn oibo ti mā nlo ọti Wain (*Wine*)—ṣé Wain Ọpẹ *Palm Wine* ni orukọ Ẹmu tiwa yi ni ede Gẹsi? ——Hẹ-ẹn-ẹn! Ẹ mā ba mi ka iyoku niṣo!!

Ha! Mo fẹrẹ gbagbe tan; ọrọ ti mba ro ki m' to rò ẹfọ? *Ifa* Ọrunmila pāpa ti a mbọ ni ilu wa—nwọn ni "Ara Ifa ni Fatùmọ wà" toto o; ṣe ẹka Ifa kan ni *Ifa Adiji* ti a ti nki yi nā jẹ! Tani ha mọ pe lati ara Igi Ọpẹ ni Ikin Ifa—Ekurọ mẹrindi-logun—ti wa? Bi nwọn ba nki i pe:—

"Ọpẹ̀ l' o ni ilẹ o.
Ọpẹ̀ l' o ma ni ilẹ"

Bi Ọpẹ ni ilẹ o, bi ko ni ilẹ o? Ẹnikẹni ti o ba fi ori le ọna oko ti o ba nka Igi Ọpẹ bi o ti pọ to pẹlu awọn oriṣiriṣi igi mī ti o ba nkàn gẹgẹ bi o ti nlọ ni yio mọ daju pe, Ọpẹ l' o n' ilẹ ni apa Ilẹ tiwa yi nitotọ. Ẹniti ko si le rin lọ si oko, ti o ba ti le wọ reluwe lati Oke Ebute Mẹta, ki o si mā kiyesi awọn igi ti o wa ninu igbo ni apatun ati apasi bi ọkọ ti nlọ titi de Alagada, bakanna ni: Ọpẹ, Ọpẹ, Ọpẹ, titi lọ̀ su-u-u ni l'aiọiye. Ṣugbọn a gbọ pe oibo kan ti daba ati mā lọ ka igi Ọpẹ ti o wa ni Ilẹ Ijọba Ẹgba, a ko gba ọrọ nā gbọ rara bi irọ ni i bi otitọ ni i, a ko le sọ pato rẹ. Bi o ba jẹ bẹ ẹ̀ nitọtọ, a ba bēre pe, melo l' a o ka ninu ebin Adepele?

T' inu irun, T' ole oje
Egbejila erigi
L' o f' ori mulẹ lai yọ
A ka ikà tan
L' ọmọde i ka we ọgbọn.

Ọdun mẹjọ ti nwọn ti nka a, wọn ko ti i ni i de idata Igi Ọpẹ ti o wa ni Ilẹ Ẹgba nikan. Ogede Ọpẹ ti Wasimi ati Awowò nikan to ka l' ọdun meji gbako, "ṣe n' ọ̀n a fi yēni ti bẹni." Awọ́n ni i, ko wa ara-ẹran.

Koi ti pari.

---

# AWỌN AKEWI.

OR

# YORUBA PHILOSOPHY.

—o—

## IYA.

Abahun ko l' ọwọ,
O l' oun o jà?
Ẹni ti ko lowo lọwọ,
Ti mbinu, ti nleri:
Ẹtẹ l' o fẹ ri!
Enia ti ko le mu ni,
Ti i ndena de ni;
Iyà ni yio jẹ kun 'yà.
Iyà meji ni i jẹ̀
A f' ada pa ' Kún;
Ikun salọ,
Ada wọ 'gbẹ.
Iya mẹta oru:
O k' ẹsẹ bọ 'mi,
O ṣeb' ẹrẹ ni i
O fọwọ ba a wo
Pe, k' oun fi run 'mu
Ṣu-u l' o kiwọ bọ 'nu!
Iya ko le e tan.
Nibit' ọlẹ gbe njẹ ẹ!
A sa paṣan mẹwa silẹ
A f' ikan kan agogo:
O l' ara kan oun go-go-go!
Mẹsan yoku nkọ?
Ara tani mā gbo si?
Ẹniti ko mọ ' we—
Ẹ ma ku iyà,
Iwe ni nwọn fi ngbọn ' yà:
Gbọn 'ya nu,—gbọn 'ya nù:
Iya njẹ ẹ, o mi j' ẹkọ?

*All Rights Reserved.*

## Kano.

S. O. Odutọla

Awọn Ijọ Holy Trinity, Kano, pade n' agogo marun abọ 5 30 p.m. ni irọlẹ Satide 20. 7. 29 nigbati nwọn fi Ọgbẹni Odutọla pẹlu aya rẹ han gbogbo ijọ.

Eto rẹ lọ bayi :–

1 Orin 279 H C. Yoruba 92 Ibo 231 (Orin kanna l' a kọ ni orişi ede mẹta un o.)

2. Sẹkitẹri Ijọ Ọgbẹni J. E Ogodazi ti Provincial Office ka 2 Tim ori 4 ẹsẹ 1-8.

3 Pastor's Warden, Ọgbẹni H. A Paris, Postmaster Surveyor gbadura lat' ori wa (extempore.)

4. Aròyé ikini ku abọ (Welcome Address) ni Sẹkitẹri Ijọ kà ni ede Gẹsi ti wọn fi kọ, lẹhin na Ọgbẹni D. O. Sanyaolu ti Lagos Store Licensed Reader Yoruba section tumọ rẹ ni ede Yoruba Ọgbẹni G O Okolo ni ede Ibo.

5 Pastor's Warden fi Mr Odutọla han gbogbo Ijọ, lẹhin na Ọgbẹni A. A. Popoọla Senior Licensed Lay Reader Ọgbẹni Myll Abadoo ti Niger Co. ati Ọgbẹni J. O. Kerry ti Police mu alejo na Ọgbẹni Odutọla rin kiri arin awọn Ijọ awọn Olukọwa nfi mẹ̀mbà ti o jẹ orilẹ ede rẹ hân, o si bọ gbogbo wọn lọwọ pẹlu ariya

Ki wọn to şe bẹ—Hûn-bûn, Ọgbẹni Odutọla fesi sí iwe ti wọn ka si i l' eti (Welcome Address) Awọn ti wọn ré Şûkú (School) lo gbọ gbogbo kọnkọbiliti ti nwi, şugbọn enia bi emi bayi ni nrọ "Biliti" "Isimu" leti mi ọkan ninu wọn ni....kosimopolitanisimu (cosmopolitanism) ati bẹhẹ lọ.

6. Gbogbo Ijọ dide duro kọ orin Iyin Oyin (Doxology) Ọgbẹni S O Odutọla si fi Ore-ofẹ pari rẹ.

7. Lẹhin na ni wọn bẹrẹ si gbe Ti (tea) jade; nigbati wọn sọ pe ti (Tea) emi şebi omigbona t' awọn ẹ̀bo ma mu ni, afi igbati mo ri ti awọn Ledi (Ladies) mẹta Mrs Oyekan (aya Schoolmaster) Mrs M O Ajayi ati Miss Alice Popoọla ngbe Burẹdi ti wọn ti fi bọta pa loju, kẽki ati bisikiti jade bi ẹru enia mẹta A, Ijọ Holy Trinity ẹ ku ingvo o Ọgbẹni Odutọla ẹ ku ewu ọkọ o, işẹ na a jẹşe o.

Ẹni-Ọ̀wọ̀ S. A. Adediji. Alabojuto.

Rev. Adediji ti o jẹ Alabojuto Ijọ ti (Holy Trinity Kano) ati awọn Ijọ Nigeria Pastorate Association gbogbo ti o wà ni Oke Ọya nihin de sihin ni arọ Sunday 22 July a ti gbọ pe on pẹlu Mr. ati Mrs. Odutọla ni ylo de ni ọjọ Furaide 19 7 29 şugbọn a gbọ pe o fi ẹsẹ rọ́ Pẹlẹ o. ọmọlúàbí On na (Ẹni-Ọwọ Adediji) tun fi Ọgbẹni Odutọla han Ijọ Elede Gẹsi ni akoko Isin 8 a.m, Ijọ Yoruba 10 a m Ijọ Ibo 11.30 a m O gbi awọn akẹkọ Isami si ipo ni akoko Isin Yoruba 4 p.m. oju mi ko to ohun ti wọn şe ni Sọnde Şuku ni 2 p.m. ati ni Isin Ibo 5.30 p m ati ni Isin Elede Gẹsi 7 p.m. afi bi ngo ba purọ.

---

Ọgbẹni John Dada, Ọ ku nawo

Ẹni ọwọ S. A. Adedii şe isami fun ọmọ Ọgbẹni wa John Dada Ọga ninu awọn ãtãtà Telọ Sabongeri Kano lẹhin Isami ni akoko isin irọlẹ ti Yoruba Sọnde 21. 7. 29 Ọgbẹni John Dada pe gbogbo Ijọ ati awọn ọrẹ lati inu Ijọ mi. Ẹgan ni hẹ. Ogboni Dada nọwo bi Ẹlẹdà fun ti Isami na, hábà ! ! ! Lati arọ Sunday na ni wọn ti nru onjẹ kakiri Sabongeri, ọna mẹta ni wọn tẹ tebulu si ọkọkan gbà to ọgọrun enia melo ni ao kà ju pe ki a ka awọn diẹ ti a mọ lọ awọn ẹni bi:-Ọgbẹni Franks, A.C.C. Treasury ẹniti wọn yan ni Alaga Ọgbẹni E. A Adeyinka ti Police. Igbakeji Alaga. Awọn Ogbẹni M O Ajayi ti Regiment D O Sanyaolu ti Lagos Stores, V. I. Bailey, Standard Coy, (Book-keeper,) T. I. Ọlafinhan, F. A Oyewọle, D. A. Stanley Adeniyi E. A. Olubiyi, Jona Abadoo (Book keeper. Lagos Stores,) Dispenser Gonsallo (Jnr.) A. Oyekan, Teacher, ogunlọgọ mi ti a mọ ati ti a ko mọ orukọ wọn pẹlu awọn ledi (Ladies) ti o lã wọn larin ṣàṣà. Bi enia ti pọ to yi igbati olukaluku gẽji l' on dide t' o nlọ; kişe pe a sọ fun wọn pe o ti tan o. Ori şirişi ọti ti kõwa mọ̀ mu ni Ọgbẹni Dada fi tẹ wọn lọrun. Adura wa ni pe ki Ọlọrun şe ọmọ na ni ọmọ rere ati ẹlẹmi gigun ki o si pese ọmọkunrin ti a o lọ ba a yọ ayọ rẹ ni iwoyi amọdun.

Edith Tinu

Edith Tinu ọkan ninu awọn akọrin ni Kúáyà (Choir) Yoruba wọ ọkọ Satide 20.7 29, a gbọ pe o nlọ si Eko lati tun lọ bẹrẹ Şúkū. Ki Ọlọrun ma ko atunri o A ki "Iya Tinu" ati awọn ẹgbọn ati aburo ku 'le de o.

## MR. OYEDELE PROMOTED.

**"Fortunate is the man whose good deeds are recognised with rewards."**

We heartily congratulate Mr. E. J. Festus Oyedele our popular and energetic Station-master Gusau upon his recent promotion from £128 to £150—£10—£220 p.a. from 1st April 1929. Having worked with him and under him at different stations like Kaduna Junction etc. and so far as sagacity in performing his daily duties, managing his staff and intellect are Concerned are concerned we seiede this opportunity to say that Mr. Oyedele is one of the best Stationmasters possessed by the Nigerian Railway.

We know that official code is under "Festina lente" but if "Vox populi" could be taken into consideration that Mr Oyedele deserves the post of Senior Station master could not be gainsayed and I hope mercantile representatives who so value his civility and discipline will agree with me. We are confident in the officers who hold the authority of the Railway will afford our amiable S. M. steady progress and more promitions.

Thanks to the Editor for space occupied

J. T. OGUN.

Gusau 22 7. 29

## IFE

Sunday the 7th July witnessed a brillant day at Ilesa when Prince Adeyemi, Princess Adelaju Prince Aderemi, Mesars Ogunniyi, Ogunlade Showoolu, Olla and various other Bokini of Ife visited Ilesa. They were punctual at the morning Service at Iloro Church and afterwards at a reception at Ilesa Palace when the Prince and the retinue were shown over the decent and magnificent buildings of THE OWA. The OWA's attitude was praiseworthy and his inquiries after the health of THE ONI, whom he terms "Baba" to put it in his own words. How is my "Father" should not be overlooked.

The Prince of Ilesa entertained the guest most sumptuously

After bidding THE OWA farewell, they returned to Ife at 4:35 p m.

The Pastor of Iloro remarked favourably about these visitors and exhorted his congregation to emulate the good humours in them.

## Kano News.

**Y. M.C.A. Kano & Mr. S. O. Odutola, B.A. D.TH**

The above Association, viz:- Young Men Christian Association of the Holy Trinity Church, Kano, gave a very grand Reception to Mr, S. O. Odutola B.A D.Th. at 8 30 p.m. on Monday 22-7-29.

The Chairman for the function was Rev. S. A, Adediji, the Superintending Pastor of the Churches under Nigerian Pastorate Association in the North here.

The ceremony commenced with singing H. C. Hymn No. 68 verses 1-4 & 5 Type-written on slips of papers. Reading of Book of Joshua chapter 1, 1-7 by the Asst. Secretary Mr M. O. Ajayi. Emxtepore Prayer by the Chairman in the absence of Mr. H. A. Paris who came later; reading of Address by the Secretary D. A. Stanley Adeniyi suitably replied to by the guest of honour Mr. S. O. Odutola. After introducing Mr. Odutola to the Association, the Chairman gave a very glowing address at length after this, Tea was served to the satisfaction of every one present by these ladies :- Mrs. Beckley the Mistress of the Ceremony, Mrs, M. O. Ajayi madam A. Olubiyi etc. The Members of the Association present were Messrs S. J. L. Beckley President of the Association. D. O. Sanyaolu Vice Presid-ent. D. A. Stanley Adeniyi, Secretary M. O. Ajayi Asst, Secretary. A. A. Dina Finacial Secretary, E. A. Olubiyi Auditor, B. A. Makinde, S. O. Sorinmade, Toriola etc. The invitees present were Rev. S. A. Adediji Chairman, Mr. & Mrs. S. Odutola, Messrs H. A. Pairs, J. E. Ogodazi, Mr & Mrs. Oyekan Schoolmaster, Messrs Jona Abadoo, E. A. Adeyinka, J. O. Dada E. O. Kerry etc.

The table was orderly, honourable and tasteful; worthy tribute should be given to the ladies for the good arrangements and order. Long live the Y. M.C.A.

## IROHIN KANO.

Mọma Kwani ni a tun ri ni arọ Wẹsidé 17/7/29 pẹlu ọlọpa ọba lẹhin rẹ. Etiri ? nwọn ni o ji agogo, ọrun ọwọ; ẹwu aọti, sokoto, ẹwu olòru (sweater), ati ọkan ti nwọn npe ni kadigan (cadigan) ati idikù kan ni ile kúkù kan ti oruko rẹ njẹ Mark Ekpi, ọjọ gangan ti o jade lọwọn 16-7-29 ni o lọ se inkan yi o. K'a ma ba ọrọ rẹ gun lọ titi mọ: adajọ da seria ẹwọn osu mẹta pẹlu isẹ asegan fun un ni ọjọ 24-7-29.

A gbọ pe ọmọ yi wẹwọn ni Kaduna, Zaria ati Jos ri. O ha fẹ fi inu ẹwọn se ile kọ un ? Ki Ọlọrun maje ki iru ọmọ-kọmọ bẹ ẹ ya sinu iran ẹni o.

### Atòyé Nipa Ojo.

A ka ninu Yoruba News ti 26-7-29, peji 1, kolomn 2, pe ojo ti nrọ lojojumọ lati ọsẹ meji wa ni Ibadan—oni 26-7-29, lo di ijẹdogun ti a ti fi ojo kan oje gbẹhin ni Kano. Ilẹ gbogbo gbẹ hànhàn, ohun ọgbin gbogbo nrọ l' okó. Ẹrun ni yi tabi ojo ? Ewọ l' o daraju, ẹnyin èyan wa. Ojo ojojumọ ti Ibadan tabi ọda hán-ún hánún ti Kano ?

### Holy Trinity School

Ile iwe awọn ọmọde tun bẹrẹ ni ọjọ Monde 22-7-29, lẹhin ti wọn ti lo isimi ọsẹ mẹta ; a gbọ pe lọjọ ti wọn tun bẹrẹ yi, awọn Ọmọ ile iwe pọ tobẹ ti wọn ni lati da awọn ọmọ kékèké pada lọ si ile wọn, nitoripe ko si awọn olukọ to, a si wa tun gbọ pe oninure katikisti Ọgbẹni S. O. Odutọla B.A. D.TH. ko jẹki wọn da awọn ọmọ na pada, o kọ pe oun na yio ma se iranlọwọ lati ma kọ wọn. Mun gode mà ká Misa (Mr.) Odutọla. A bẹ awọn Tisa onisabiketi (Certificated Teachers) ki wọn goke wa kánkán lati ran wa lọwọ o.

### Atipakọ Egun Ibadan.

A ka ninu Iwe Irohin Yoruba News yi niwọn ọsẹ gbọgbọro sẹhin (a ko mọ ibiti a ju iwe na si mọ) pe " Ọlọkọ Atipakọ d'Onigbagbọ " a ka pe alamari (Isẹ yanu) ti Ọlọrun fi han a ni o mu ki o di onigbagbọ, nigbati o mu okun ti o lọ so ti okun ja sibẹsibẹ ti ko si ku, etc.

A si tun wa ka ninu Yoruba News ti Julae 16 paji 1 kọlọmu 1 pe Atipakọ ba awọn Egungun jade lọ ki Balẹ lọjo Egun ọdun, o si fi sasara ọwọ bẹ aja si meji ni ọjọ Julae 1 ti o o jẹ ọjọ Egun Ọdun—Njẹ, a bere, Ọlọkọ Atipakọ ha tun pada si keferi ni, tabi ọna wo, ile wo, ati yàrà wo ni Atipakọ ti jade laisi Ọlọko rẹ ?

Esi wa ni pe : Aburo Awolọwọ ọkunrin l' o tun nse Ọlọkọ Egungun Atipakọ nisisiyi,

Ọgbẹni Awolọwọ ko tun pada si ile baba rẹ mọ lati ọjọ na. Ọgbẹni na ti bẹrẹ si ma kọ ẹkọ isami nisisiyi *Ed: Y.N.*

## NEWS & NOTES.

**The Revival Meetings for Keswick Convention, Ibadan, will be observed from August 4-7 1929 by the Rev. W. C. JORDAN, M.A., Missioner. as follows:—**

August 4th Sunday, Morning Service W M.S. Agbeni Church, 4 30 p.m Aremo Church, 5th. Monday, 7.45 a.m. Bible Reading for Workers. Oke Mapo. 5 pm General Meeting, Kudeti. 6th Tuesday 7.45 p.m Bible Reading. Oke Mapo, 5 p.m General Meeting, Ogunpa. 7th Wednes. day. 7.45 p.m Bible Reading. Oke Mapo, 5 p.m General Meeting, Oke Mapo.

### THE IBADAN GRAMMAR SCHOOL SECOND BLOCK - BUILDINGS.

The Foundation Stone of the Second Block-Buildings of the Ibadan Grammar School will D.V be laid by the Honourable Captain W. A. Ross, C.M G., Senior Resident, Ọyọ Province, on Thursday afternoon the 8th instant at 4 o'clock p.m.

All are cordially invited

Isaac F. Karunwi,
*Motor Engineer,*
ONIREKE ROAD, IBADAN.
Tele Address:- 'Karunwi Brooks, Ibadan'
P. O. Box 142,

Vulcanizing of
Inner Tubes & Tyres

Undertakes repairs of Motors Machines, Typewriters, Sewing Machines, at moderate cost of the Work-manship
Terms:—(Payable before delivery)
Established 1st Jan. 1918.

ON SALE.

Nos. 6-7 and 8 of the "WASU" Official organ of the East African Students Union of London is on sale at the office of this paper. Price 1/- per copy.

Also "Africa at the Bar of the Family of Nations," by Ladipọ Ṣolankẹ, Esq., M.A., B.C.L., LL.B., Price 2/- per copy.

BEAUTIFUL HOME.

MAKE YOUR HOMES BEAUTIFUL
WITH
GOLD SEAL CONGOLEUM
*(FLOOR COVERING)*

We have just received a new supply of exquisite designs in running yards.

CONGOLEUM is guaranteed Damp Proof, Insect Proof: requires no nails and not curl or break in Harmattans.

YOUR INSPECTON INVITED.

JOHN WALKDEN & Co., Ltd.
IDDO GATE.

GBA KO TỌ WO OYIN MỌMỌ.

## Craig's Spleen Mixture 3/.

Egbogi Ọmọde.

## Craig's Menthobalm 1/6.

Awogba Arun.

Fun Ẹfọri, Otutu, Akokoro, Ibà ara riro, tabi bi iru bẹẹ

## Craig's Nature Restorer

**Nos. 1. & 2. 5/6.**

Egbogi arẹmọ ati ajidewe wọn mbẹ in Ile Egbogi

IṢẸ Olodumare.

**P.O. Box 64. Ibadan, Nigeria.**

Ajẹ bi idan ni gbogbo wọn, ya wa mu tirẹ, Ọrẹ

J. O. Ade: Craig.
*Chemist & Druggist*
Established 1916.

BRANCHES AT
AGBENI, OSOGBO
& LAGOS.

---

# WANTED.

Two Certificated Teachers.

**Apply to P. O. Box, 82,**
**Ibadan.**

---

# ON SALE.

IWE KINNI
TI
AWỌN AKEWI
OR
(*YORUBA PHILOSOPHY*)

Price 8d. Post Free 9d.

Obtainable at

The C.M.S. Bookshop,
Lagos & Branches.

"Eleti Ọfẹ," Offices,
71 Osbodi St. & 13 Victoria Rd.
Lagos.

Also at The Ilarẹ Press
Ajaba Square, Ogunpa Road, Ibadan.


Printed and Published by D A. Ọbasa at The Ilare Press, Ogunpa Road, Ibadan.